# AJỌ AGỌ

## Lefitiku 23:33-44; Numeri 29:12-39;
### Deuteronomi 16:13-17; Ifihan 14:14-20
### ẸKỌ 88 – FUN AGBA

**AKỌSORI: "OLUWA Ọlọrun rẹ yio busi i fun ọ ni gbogbo asunkún rẹ, ati ninu gbogbo iṣẹ ọwọ́ rẹ, nitorina ki iwọ ki o ma yọ̀ nitõtọ" (Deuteronomi 16:15).**

**I Ajọ Agọ tabi Ajọ Ikorewọle**

1. A maa n ṣe ajọ yii ni ọjọ kẹẹdogun oṣù keje fun ọjọ meje lẹyin akoko ikore, Lefitiku 23:33, 34; Ẹksodu 23:16
2. Ọjọ kin-in-ni ati ọjọ kẹjọ jẹ́ ọjọ́ apejọ mimọ́, a si maa n ṣe irubọ ni awọn ọjọ ti o wà laaarin wọn, Lefitiku 23:35, 36, 39
3. Gbogbo Israẹli ni ki o maa yọ̀ lori eso asunkún ti Ọlọrun fi fun wọn, Deuteronomi 16:13-15; Lefitiku 23:40
4. Gbogbo awọn ọkunrin ni wọn gbọdọ farahàn, olukuluku a mu ọrẹ wá gẹgẹ bi ibukun OLUWA, Deuteronomi 16:16, 17; Ẹksodu 23:17; 34:23, 24
5. Ẹbọ sisun, ẹbọ ohun jijẹ ati ẹbọ ẹ̀ṣẹ ni wọn maa n mú wá lojoojumọ, irubọ wọnyii si maa n gba igba ẹran o din kan (199), Numeri 29:12-39; Lefitiku 23:37

**II Ajọ ti a maa n Ṣe labẹ Atibaba tabi ninu Agọ**

6. A maa n fi ẹka igi, imọ ọpẹ, ati igi wilo kọ́ awọn búkà naa, Lefitiku 23:40; Deuteronomi 8:14-18
7. Ajọ naa jẹ́ iranti igba ikẹkọọ Israẹli ni aginju laaarin aṣalẹ gbigbona, Lefitiku 23:41-44

**III Ajọ naa jẹ́ Apẹẹrẹ "Ikore" ti Ikẹyin Ayé**

8. Olukore farahàn ni awọsanma funfun gẹgẹ bi Ọmọ-eniyan, pẹlu doje mimú kan, Ifihan 14:14; Matteu 24:30
9. A kede lati kore nitori ikore ayé ti pọ́n, Ifihan 14:15, 16; Matteu 24:30, 31; 13:41, 42; Marku 4:26-29
10. Olukore miiran tun farahàn, ti i ṣe angẹli kan ti o ni doje mimú pẹlu, Ifihan 14:17; Matteu 13:49
11. A kede rirẹ́ ìdì èso ajara pẹlu nitori wọn ti pọ́n tán, Ifihan 14:18
12. A kó wọn lọ sinu ifunti a si tẹ̀ wọn lẹyin odi ilu naa, Ifihan 14:19, 20; Isaiah 63:1-4

## ALAYE

Ikore oko ni Ilẹ Ileri naa n tẹle ara wọn ni ira-ira fun akoko ti o gùn pupọ. Wọn a bẹrẹ pẹlu ikore barli ni oṣu kin-in-ni titi fi di akoko alikama, igba kikó eso àjara, olifi, eso ọpọtọ, pomegranate ati awọn eso miiran gbogbo titi di oṣu keje; nigba yii ni wọn yoo ni ikorewọle nlá nlà ohun wọnni ti Ọlọrun pese fun Israẹli ni ọdọọdun. A dá ajọ agọ silẹ, lọna kin-in-ni, lati rán Israẹli leti oore Ọlọrun si wọn ati lati fun wọn ni ọkàn ọpẹ si I fun ipese nla Rẹ̀, o fara jọ Ọjọ Idupẹ ti a n ṣe nigba ti ọdun n lọ si opin.

**Awọn Ilana ti a n Pamọ Ṣaaju Ajọ Agọ**

Iró ipè ni o ṣiwaju ajọ yii ni ọjọ kin-in-ni oṣu keje, lẹyin naa ni Ọjọ Nla Ọjọ Etutu ni ọjọ kẹwaa, eyi ti o jẹ ọjọ ọ̀fọ̀ fun gbogbo Israẹli eyi ti wọn o ranti ẹ̀ṣẹ wọn atẹyinwa ti wọn yoo si ṣe aṣaro aanu Ọlọrun ti o pese Etutu naa nipa eyi ti wọn le fi bá Ọlọrun laja. Lẹyin naa ni ọjọ kẹẹdogun oṣu ni ajọ agọ bẹrẹ, wọn o si fi ọjọ meje ṣe e, ọjọ kẹjọ ni ọjọ apejọ mimọ́. Eyi jẹ́ akoko ayọ̀ ati iyin si Ọlọrun fun oore Rẹ̀ nipa ti ara ati nipa ti ẹmi. Bawo ni ipin Israẹli i ba si ti jẹ àṣàyàn ati iyatọ tó bi o ba ṣe pe wọn pa ẹmi-ajọ yii mọ́ ninu ọkàn wọn ti wọn si gbọran si aṣẹ Ọlọrun Ẹni ti o fi ohun rere gbogbo tẹ́ wọn lọrun. Wọn i ba le kọrin iyin bi ti Dafidi pe: "OLUWA li Oluṣọ-agutan mi; emi ki yio ṣe alaini. O mu mi dubulẹ ninu papa-oko tutù; o mu mi lọ si iha omi didakẹ rọ́rọ́."Ni ọjọ kọọkan laaarin ajọ yii, Israẹli ni lati mú ẹbọ sisun, ẹbọ ohun jijẹ, ẹbọ ohun mimu ati ẹbọ ẹ̀ṣẹ wá fun OLUWA lẹyin ẹbọ atinuwa wọn lati inu ọkàn imoore. Wọn ni lati kọ́ àtíbàbà ninu eyi ti olukuluku wọn yoo gbé laaarin ọsẹ yii, lati rán wọn leti ọdun wọnni ti wọn fi kẹkọọ lẹyin idande wọn kuro loko ẹru Egipti, ti wọn n rin kiri ninu aginju, ti wọn si n gbé ninu agọ.

**Ohun Pataki ti Ajọ naa nṣe Apẹẹrẹ**

Ajọ agọ, gẹgẹ bi ajọdun meji ti o ṣiwaju rẹ̀, ni ẹkọ ti o tayọ rekọja Israẹli o si n tọka si ohun nla ti yoo ṣẹlẹ ni ọjọ kẹyin. Johannu ẹni ti a fi iṣipaya naa fun ri iran olukore kan ni awọsanma, ti o dabi Ọmọ-eniyan. "Angẹli miran si ti inu tẹmpili jade wá ti nke li ohùn rara si ẹniti o joko lori awọsanma pe, Tẹ̀ doje rẹ bọ̀ ọ, ki o si mã kore: nitori akokò ati kore de, nitori ikorè aiye ti gbó tan" (Ifihan 14:15). Jesu paapaa sọrọ nipa ọjọ nla ọjọ "ikore" yii nigba ti O n sọ ti ikẹyin ọjọ: "Nigbana li àmi Ọmọ-enia yio si fi ara hàn li ọrun; nigbana ni gbogbo ẹya aiyé yio kãnu, nwọn o si ri Ọmọ-enia ti yio ma ti oju ọrun bọ̀ ti on ti agbara ati ogo nla. Yio si rán awọn angẹli rẹ̀ ti awọn ti ohùn ipè nla, nwọn o si kó gbogbo awọn ayanfẹ rẹ̀ lati ori igun mẹrẹrin aiye jọ, lati ikangun ọrun kan lọ de ikangun keji" (Matteu 24:30, 31). Eyi ni ikorewọle nla ti awọn "ayanfẹ" sọdọ Rẹ̀. Ta ni si le mọ̀ bi iro ipe ti o ṣiwaju ajọ agọ jẹ apẹẹrẹ ohùn ipe nla ni ti yoo kede ikorewọle awọn ayanfẹ Ọlọrun? Bakan naa pẹlu ni Ọjọ Etutu n tọka si Ọdọ-agutan (Ọlọrun) ti a pa, lai si Rẹ̀ ki bá ti si ikore awọn ayanfẹ kankan. Ọdọ Agutan ni Ẹni pataki ti ọpọlọpọ ẹda ti o yi itẹ ká n fi iyin fún, "Nwọn nwi li ohùn rara pe, Yiyẹ li Ọdọ-Agutan na ti a ti pa, lati gbà agbara, ati ọrọ̀, ati ọgbọ́n, ati ipá, ati ọlá, ati ogo, ati ibukun" (Ifihan 5:12).

**Ikore Nla Keji**

Ṣugbọn Johannu ti a fi iṣipaya fun sọ fun wa nipa "ikore" keji ti yoo ṣẹlẹ ni ikẹyin ọjọ: "Angẹli miran si ti inu tẹmpili ti mbẹ li ọrun jade wá, ti on ti doje mimu. Angẹli miran si ti ibi pẹpẹ jade wá, ti o ni agbara lori iná; (eyi n sọ nipa idajọ); o si ke li ohùn rara si ẹniti o ni doje mimu, wipe, Tẹ̀ doje rẹ mimu bọ̀ ọ, ki o si rẹ́ awọn idi ajara aiyé nitori awọn eso rẹ̀ ti pọ́n. Angẹli na si tẹ̀ doje rẹ̀ bọ̀ ilẹ aiye, nitori awọn eso rẹ̀ ti pọ́n. Angẹli na si tẹ̀ doje rẹ̀ bọ̀ ilẹ aiye, o si ké ajara ilẹ aiye, o si kó o lọ sinu ifúnti, ifúnti nla ibinu Ọlọrun. A si tẹ̀ ifúnti na lẹhin ode ilu na, ẹ̀jẹ si ti inu ifúnti na jade, ani titi de okùn ijanu ẹṣin jinna to ẹgbẹjọ furlọngi" (Ifihan 14:17-20). Gẹgẹ bi ibinu Ọlọrun ti tobi rekọja si ẹ̀ṣẹ, bakan naa si ni aanu Rẹ̀ si awọn ẹlẹṣẹ.

**Awọn ti o Ṣegbe ni Aginju ati awọn ti o Ṣẹgun**

Awọn àtibàbà ti a fi ẹka igi kọ́ ninu eyi ti awọn Ọmọ Israẹli n gbé ni akoko ajọ agọ rán wọn leti iriri ogoji ọdun ni aginju, boya o si tun rán awọn ogo wẹẹrẹ wọn, ti wọn de ilẹ ileri leti, nipa awọn baba wọn ti o kuna nipa aigbagbọ́, lati jẹ́ ipe giga Ọlọrun ti wọn si ṣegbe ni aginju. Ohun ẹru ni lati kuna anfaani oriṣiriṣi ti o wà ninu Kristi Jesu. Jeremiah sọ fun wa nipa awọn eniyan kan ti n kigbe pe, "Ikore ti kọja, ẹ̀run ti pari, a kò si gba wa la" (Jeremiah 8:20). Ṣugbọn awọn miiran wà nigba Majẹmu Laelae, "awọn ẹni nipasẹ igbagbọ́ ti nwọn ṣẹgun ilẹ ọba, ti nwọn ṣiṣẹ ododo, ti nwọn gbà ileri, ti wọn dí awọn kiniun li ẹnu. Ti nwọn pa agbara iná, ti nwọn bọ́ lọwọ oju-idà, ti a sọ di alagbara ninu ailera, ti nwọn di akọni ni ija, nwọn lé ogun awọn àjeji sá. Awọn obirin ri okú wọn gbà nipa ajinde: a si dá awọn ẹlomiran lóro, nwọn kọ̀ lati gbà idasilẹ; ki nwọn ki o le ri ajinde ti o dara jù gbà: Awọn ẹlomiran si ri idanwò ti ẹsín, ati ti inà, ati ju bẽ lọ ti ìde ati ti tubu: A sọ wọn li okuta, a fi ayùn rẹ́ wọn meji, a dán wọn wò, a fi idà pa wọn: nwọn rìn kákiri ninu awọ agutan ati ninu awọ ewurẹ; nwọn di alaini, olupọnju, ẹniti a nda loro; (Awọn ẹniti aiye kò yẹ fun): nwọn nkiri ninu aṣálẹ, ati lori òke, ati ninu ihò ati ninu ihò abẹ ilẹ. Gbogbo awọn wọnyi ti a jẹri rere si nipa igbagbọ́, nwọn kò si ri ileri na gbà: Nitori Ọlọrun ti pèse ohun ti o dara jù silẹ fun wa, pe li aisi wa, ki a má ṣe wọn pé" (Heberu 11:33-40).

**Imuṣẹ Ajọ Agọ**

Ekinni ninu awọn ajọdun mẹta wọnyii, ti i ṣe Ajọ irekọja ni a mú ṣẹ patapata nigba ti Jesu wọ Jerusalẹmu ni ọjọ kẹwaa oṣu Abibu, a si kan An mọ́ agbelebu, O kú ni deedee wakati ẹbọ aṣaalẹ ni ọjọ kẹẹdogun. Ajọ keji ni a mú ṣẹ ni aadọta ọjọ lẹyin naa ni Ọjọ Pẹntekọsti, nigba ti Ẹmi Mimọ́ sọkalẹ bi iro ẹ̀fuufu nla, ti awọn ọgọfa eniyan ni yara oke si gba agbara lati ṣiṣẹ; eyi ni ipilẹṣẹ ijọ Kristi, ti a si kede Ihinrere ni gbangba fun gbogbo orilẹ-ede Keferi. Ẹkẹta awọn ajọdun naa ni ajọ agọ, ti a o muṣẹ nigba ti Oluwa ba pada bọ̀ lẹẹkeji ti O si fi idi Ijọba Rẹ̀ ẹgbẹrun ọdun kalẹ, ti a o si mu ifẹ Ọlọrun ṣẹ ni ayé gẹgẹ bi ti Ọrun. "Yio si ṣe, olukuluku ẹniti o kù ninu gbogbo awọn orilẹ-ède ti o dide si Jerusalẹmu yio ma goke lọ lọdọọdun lati sin Ọba, OLUWA awọn ọmọ-ogun, ati lati pa àse agọ wọnni mọ" (Sekariah 14:16).

**AWỌN IBEERE**

1. Akoko wo ninu ọdun ni wọn n pa ajọ agọ mọ́, iranti ki si ni pipamọ rẹ̀ i ṣe?
2. Ki ni ṣe ti awọn Ọmọ Israẹli n kọ́ àtibàbà ti wọn si n gbé inu rẹ̀ ni akoko ajọ yii? Ọjọ meloo ni wọn fi n ṣe e?
3. Ewo ni ọjọ ti awa n kiyesi ni ilẹ wa ti o fara jọ ajọ agọ yii?
4. Awọn ọrẹ wo ni a n mú wá lojoojumọ fun OLUWA lati ya ajọ yii si mimọ́? Apẹẹrẹ ki ni awọn ọrẹ naa jẹ́?
5. Ki ni ohun pataki ti Ọlọrun fẹ mu jade nipa ajọ agọ ti O dá silẹ fun awọn Ọmọ Israẹli?
6. Ẹkọ wo ninu Majẹmu Titun ni ajọ agọ jẹ́ apẹẹrẹ rẹ̀?
7. Awọn ilana meji ti o ṣiwaju ajọ agọ wo ni a n pamọ ni oṣù keje? Bawo ni a si ṣe mu wọn ṣẹ ninu awọn ẹkọ Majẹmu Titun?
8. Awọn ajọdun mẹta pataki wo ni a dá silẹ ti awọn ọmọkunrin Israẹli gbọdọ farahàn nibẹ?
9. Èwo ninu awọn ajọdun wọnyii ni a ti mu ṣẹ? Sọ nipa imuṣẹ wọn.
10. Nigba wo ati ni ọna wo ni a oo mu eyi ti o kẹyin ninu awọn ajọdun mẹtẹẹta wọnyii ṣẹ? Fi Iwe Mimọ́ gbè é lẹsẹ.